# Idahun Alfa Bọlaji Akewukewe si ọrọ Evangelist Akande

ABU Hanifat si jẹri si i bẹ ẹ ni TẸFUSIRI SAWI pẹlu. Ọlọrun sa sọ ni Surat 25 ayat 33 (o jẹ ẹsẹ 34 ninu Alkurani oruba ti Rev. M. S. Cole). Ninu ayat Alkurani yi ni Ọlọrun gbe fi han pe, On ma a nsọ TẸFUSIRI ti o dara kalẹ fun ẹ (Anabi wa ti on fi Alkurani ranṣẹ si). Itumọ ti Alkurani lona ti o darajulọ ni o njẹ TẸFUSIRI. Gbogbo ẹniti o ba ka ọrọ ti mo fi fun Akande lesi ni 23-11-58 ati esi kande, yio mọ pe, Kantankantan ni esi ti Akande nfọ si i bi abọ ẹkọ ti ma a ngmu alaabọ ẹkọ kọṣẹ lọsangangan.

Mo ti sọ ninu esi ti 23-11-58 pe, ẹlẹsẹkan kole ba ẹlẹsẹ meji fẹsẹ wọnsẹ ki o ma ṣubu, nitoripe ẹniti o mọ iwe ati kewu ni ẹlẹsẹ meji ẹ ko ha nri ẹsin ati ẹlẹya Akande 'nu Iwe Irohin bayi bi o? Ki Akande fi Iwe Owe ori 11 ẹsẹ 2 kọgbọn ti o wipe "Bi igberaga ba de, nigbana ni itiju de, ṣugbọn ọgbọn wa pẹlu onirẹlẹ" ki Akande kọ bi a ti ṣe hu iwa irẹlẹ.

A dupẹ pupọ lọwọ Ọlọrun pe, Akande gba pe aṣiṣe pupọ wọnyen wa nfi Bibeli repẹtẹ bẹ ẹ, eyiti o pania lẹrin ninu ọrọ Akande ni siso ti o nsọ pe, awọn aṣiṣe wọnyen ko le mu enia ṣina ati pe, ko le sọ enia di ọta Ọlọrun. Nitori eyi, mo bi Akande lere pe, ariyanjiyan Bibeli ti nko arẹ okan ba enia, ti ko jẹki enia le mọ otitọ Bibeli, ko ha je ohun buburu ti mba igbagbọ awọn enia jẹ bi o? Arẹ okan na ni o mu ẹnyin Kiriyo aiye gbe ofin Ọlọrun sọ si ẹhin ti ẹ ko fi mu u ṣe mọ gẹgẹbi awọn aṣiwaju nyin ti iṣe tẹlẹri. Nehemiah ori 9 ẹsẹ 26.

O tọ ki ẹnyin Kiriyo bẹru ogun Ọlọrun ti o wa ninu Deuteronomi ori 28 ẹsẹ 15 de 40, lori ẹniti o ba kọ lati pa ofin Ọlọrun mọ. Jesu sa ti sọ pe "Ohun kikini kan ninu ofin Ọlọrun ki yio kọja laijẹpe ọrun on aiye ba kọja" Matteu ori 5 ẹsẹ 17 de 21. Akande sọ pe Alkurani kọ enia lẹkọ buburu, iro ! ko boju rara ni eyiyi jẹ, ko si ibiti o kọ enia ni ẹkọ buburu 'nu Alkurani lati oke de ilẹ. Bibeli ni o tilẹ kọ enia ni ẹkọ buburu. Ko si ẹniti o le ka Matteu ori 12 ẹsẹ 1 de 4 pe, "Jesu ko awọn ọmọ-ẹhin rẹ lọ si oko-oloko lọ ya ọka-ọloka jẹ" ti ko ni iro irokuro lori ofin Ọlọrun ti o sọ pe, "Iwọ ko gbọdọ jale" ati pe, "Iwọ ko gbọdọ ṣe ojukokoro si gbogbo ohun ti iṣe ti ẹnikeji rẹ" Eksodu ori 20 ẹsẹ 15 de 17.

Ko si ẹniti yio ri iru esi ti Bibeli sọ pe Jesu fun iya rẹ ninu Johannu ori 2 ẹsẹ 1 de 4 ti ko ni i ro irokuro lori ofin "Bọwọ fun baba on iya rẹ". Ekisodu ori 20 ẹsẹ 12. Ko si ẹniti yio ti gbọ iwasu Kiriyo tẹlẹ pe, "Jesu mọ ohun gbogbo" Johannu ori 16 ẹsẹ 30 ti yio tun ri i ka pe, Jesu ko fi agbara imọ rẹ mọ bi ọpọtọ so eso lokere bi ko so eso, depo ti o fi nṣe bi boya on yio i nkan jẹ lori rẹ ti ko si ri Marku ori 11 ẹsẹ 12 de 14 ni ko ni ṣiyemeji nipa ẹkọ ninu gbogbo agbara imọ rẹ, tabi fifi ti o fi iṣẹ iyanu mu igi na gbẹ lẹsẹkẹsẹ ti ko si ṣe rere ti mimu igi na so eso ti on iba si fi jẹ ajẹyo ti ebi ti npa a ti ẹlomiran iba si ma a fi eso rẹ ṣe anfani.

Bibeli li o kọ wọn li ẹkọ buburu ti "ririun ọkunrin, obirin ati awọn ọmọ wẹwẹ patapata nitori aigba ẹsin" Deuteronomi ori 3 ẹsẹ 1—7 ati ori [illegible] ẹsẹ 34. Bibeli ko nyin li ẹkọ buburu pe, "Jesu ko wa a ran alafia" Matteu ori 10 ẹsẹ 34 ati Luku ori 12 ẹsẹ 49 de 53. Akande tun pa iro nla pe," lati ọdun ti Alkurani ti wa li ede Larubawa, ede kan na li o wa, pe nwọn ko tumọ rẹ si ede kankan laiye" Musulumi ti tumọ Alkurani si ede miran laiye: bi si ede HIDNU ni INDIA, si ede Oyinbo ati bẹẹ bẹ ẹ. Ti ede Yoruba ni awa Musulumi ilẹ Yoruba nṣe lọwọ. Ohun ti o jẹki a pẹ to bayi ni pe, ki o ma fi le jẹ itukutu bi i ti Bibeli ati Alkurani Rev. M. S. Cole ti o je itukutu.

Akande bu gbogbo Imale papọ tori pe o je ẹlẹrẹkẹ-eebu, o sọ pe gbogbo wa ko ni ọgbọn tori ti a ko fi le tumọ Alkurani, bi eebu ba ndun awọn Musulumi ẹlẹgbẹ mi, awọn na yio gbọn iwosi eyini danu nipa riran MUJAHIDUNA ISLAMIATI ti o ti pari itumọ Alkurani Yoruba lọwọlọwọ ti nwọn si wa lori adehun rẹ pẹlu "GERMANY" ti nwọn npe ipe fun iranlọwọ owo kun iba ti nwọn ni. Ọlọrun jẹki iṣorisi rẹ soju emi awa pẹlu Akande (Amin).

...Akande sọ pe Surat 5 ayat 5' wipe, "ki Imale ma a mu awọn JUU ati Kristiani li ọrẹ (alaabọ), bi ahesọ-

(Wo oju ewe kẹjọ)

NO. 25

## FEDERAL ELECTIONS 1959

### REGISTRATION OF ELECTORS

### WESTERN REGION

Registration of electors will take place in Western Region between

## FEBRUARY 16TH — MARCH 14TH 1959.

During this period Registration offices will be open in all Constituencies at hours to be announced on official posters.

*You cannot vote unless You register now.*

Bi o ba fẹ lati gbadun Ra BICYCLE Siga Naijiria ti o l'okiki




OSTERMILK

njẹki ọmọ-ọwọ nitẹlọrun ! lagbara ! lokun ninu !




Iya ko le fun ọmọ-ọwọ lọnjẹ mọ, ọpẹlọpẹ [illegible] wara Ostermilk. Ostermilk, wara ti o dara lonjẹ, o le mu ki ọmọ-ọmọ rẹ lagbara ki o si ni itẹlọrun pẹlu. O ni afikun onjẹ okun-inu pupọ (extra vitamin—extra iron). Maṣe daamu. Ostermilk ma a nwa ni akọtun ṣe ju wara lasan lọ— nitori nwọn nde apolo rẹ pa dada. Ṣa ti fi oruk pe Ostermilk— —fun ọmọ-ọwọ nu——wa a si ri ọmọ na ti yio ma a rerin musẹ-musẹ.

OSTERMILK

MADE BY GLAXO LABORATORIES LTD., GREENFORD, ENGLAND

Agent: R. E. HARDING AND CO. LTD., 38 COMMERCIAL AVENUE, YABA, LAGOS AND ALSO PRIVATE MAIL BAG, ABA.

# Akiyesi awọn Awo-Irawọ nipa Ọjọ-Ibi

AWỌN nkan wonyi ni yio sẹlẹ larin ọsẹ yi February 22nd—28th, 1959 si awọn ti ọjọ'bi wọn ba bọsi arin awọn ọjọ ọsu ti a daruko si isalẹ wonyi:—

## CAPRICORN
**(DEC. 21ST—JAN. 19TH)**

Nwọn fi lẹta kan ṣe eto nkankan ti yio gbe ẹ ga l'aiye. Bi o ba nwaṣẹ tabi o fẹ lati gba agbaṣe titun kan, gbogbo rẹ yio bọsi i dada. Ko ni lati si iyemeji nisisiyi, bi o ti wu ki awọn iṣoro rẹ le to, o nṣe dada ninu igbesi-aiye rẹ.

## AQUARIUS
**(JAN. 20TH—FEB 18TH)**

Eyi le jẹ ọsẹ ti o le ninu gbogbo awọn ohun ti o jẹmọ ti ara rẹ kuku gba otitọ pe o ni ipinnu nla kan lati ṣe ki o si ṣe e lai jafara. Bi o ba ni aye lati rin irin-ajo laipẹ ọjọ se be ẹ laisi ariyanjiyan (argument).

## PISCES
**(FEB 19TH—MAR. 20TH)**

O dabi ẹnipe iṣẹ yio po fun ẹ ninu ọsẹ yi, owo rẹ yio si di pupọ nipa awọn ọran ara rẹ. Maṣe tapa si imọran rere ti awọn ti o ba dagba ju ẹ lọ tabi ti nwọn ti i iriri ju ẹ lọ. Yio jẹ iwa omugọ lati lọ si ọrẹ tabi olufẹ yan.

## ARIES
**(MAR 21ST—APL. 20TH)**

Ibẹrẹ ọsẹ yi dabi ẹnipe yio le yio si mu wahala dani. Nikehin wa a ni isinmi, wa a wa ri pe, gbajumọ rẹ ju bi o ti ni ero si lọ. Ọsẹ yi dara fun ẹgbẹ siṣe lehinti nwọn ba ti fi ẹ han awọn enia tabi lẹhinti nwọn ti ṣe eto ifoju-koju ba ara ẹni sọrọ.

## TAURUS
**(APL. 21ST—MAY 20TH)**

Imọran lati ṣipo pada kuro nile tabi lati ri iṣẹ titun ṣe nfarahan were-were. Ọrẹbirin rẹ kan le fun ẹ ni imọran kan tabi ṣe ifihan kan fun ẹ ti yio jẹ iranlọwọ fun ẹ ni ọna rẹ. Nipa ọran ti o jẹmọ ile ati ẹbi, o jẹ ọranyan fun ẹ lati tubọ ṣe suru diẹ si i.

## GEMINI
**(MAY 21ST—JUNE 20TH)**

Ọsẹ yi ni lati jẹ eyiti yio soro fun ẹ lori ohun titun ti o ni ero si lati ṣe. Ohun kan ti o ti ngbero nipa rẹ lati igba diẹ sẹhin fojuhan pe yio ba ode oja-tita mu. Iṣoro rẹ nisisiyi ni lati ni iranwọ ti o to ati owo ti o to o lo dada.

## CANCER
**(JUNE 21ST—JULY 20TH)**

Ma a ṣe ifura dada ninu awọn ọjọ ti yio bẹrẹ ọsẹ yi. Afi bi o ba ni ifura dada ni ko ni jẹ ki o padanu anfani a ti owo. Nipa ohun ti o jẹmọ ẹgbẹ, ọjọ meta ti o kẹhin ninu ọsẹ yi darajulọ fun ẹ. Fi iye ti o ba ni pamọ nigbati o ba nṣe adehun titi di igbana.

## LEO
**(JULY 21ST—AUG. 21ST)**

Nitooto ọkan rẹ ni lati balẹ nisisiyi lori awọn ọran rẹ, sibẹsibẹ awọn nkan miran wa fun ẹ lati ṣe eto wọn pari. Ninu ọsẹ yi wa a ṣe eto kan ti o farakọ ẹbi ati owo (money) pẹlu. Ọsẹ yi dara fun ẹ lati ṣe eto awọn ọjọ isinmi, irin-ajo tabi ẹgbẹ.

## VIRGO
**(AUG. 22ND—SEP. 22ND)**

Wa a pari iṣẹ kan, wa a si bẹrẹ omiran. Lakokoyi wa a mọ pe, iyipada titun nde si igbesi-aiye rẹ. Bi o ba mu suru dada to ti o si ni aanu, ọrẹ ojowu le di ọrẹ kori-kosun tabi ọrẹ ododo.

## LIBRA
**(SEPT. 23RD—OCT. 23RD)**

Nitoto ailera le yọ ẹ lẹnu diẹ, sibẹ-sibẹ ọsẹ yi ni lati dara fun ẹ paapa ni. Wa a mọ pe eto igbele tubọ ndogba si i dada, agbekẹle rẹ si tubọ fi idimulẹ. Awọn ọrẹ rẹ sowolu pẹlu awọn ẹbi rẹ lati le ṣe iranlọwọ si idunnu rẹ.

## SCORPIO
**(OCT. 24TH—NOV. 22ND)**

Ọsẹ ti IYIPADA pupọ wa ninu rẹ; nkankan ti yio gbe ẹ lọ si ibi titun yio sẹlẹ. Maṣe gbidanwo lati yẹra fun awọn eto titun nigbati nwọn le mu owo pupọ wale fun ẹ ju eyiti o ti gbadun tẹlẹ ri lọ. Ni ipari ọsẹ yi wa a ma a ṣe iyanju awọn iṣoro ti o jẹmọ iṣẹ, wa a si ma a ri owo (money) ko jọ.

## SAGITTARIUS
**(NOV. 23RD—DEC. 20TH)**

Irin-ajo le wa fun ọ ninu ọsẹ yi tabi ki o ṣe alabapade alejo tabi ara idalẹ kan. Eyikeyi ti o le ṣẹlẹ, o ti wa ni imura silẹ fun awọn eto nkan titun. Ọjọ meji ti o kẹhin ninu ọsẹ yi jẹ pataki fun ohun ti o jẹmọ ẹgbẹ. Jẹki irisi rẹ ma a fa enia mọra, ki o si ma a tu awọn enia loju.

Ohun ti o dara julọ
lati fi ṣe awọn ọrẹ rẹ lalejo ni
BLACK PRINCE
Schiedam Aromatic Schnapps





O daju pe apejọ ẹgbẹ rẹ a yori dada ti o ba fi BLACK PRINCE Aromatic Schnapps ti o gbadun julọ ṣe won lalejo. O ti lokiki yika gbogbo aiye gẹgẹbi ohun mimu ti o dara ti ko si lewu ninu. O si jẹ ogun atẹjẹṣẹ ti o nfun ni lagbara.

DA AN WO LONI

OVALTINE

Ntun agbara ati okun-inu ṣe




DWA215

The truck for BIG loads!

Mọto MORRIS oni tọnun meje ko gbogbo agbara miran papọ gẹgẹbi awọn anfani ti o wa ninu ṣiṣe rẹ

MORRIS 701 DIESEL



Mọto akeru ti o dara julọ nisi fun awọn ẹru ti o ba lobi gidi. Opolopo awọn anfani rẹ nlanla ni. Agbara fun ọwọ mọto lati wa a ni irọrun, agbara fun ijanu ti o daju, ikoko ti o gba epo pupọ fun irinajo jijinna ati aye irọrun fun awa-moto. Wọnyi jẹ diẹ ninu anfani ti o mu ki moto na fi darajulọ lati fi ẹru ṣowo pẹlu ẹndinwo.

Ranṣẹ fun un nisisiyi lati ọdọ C·F·A·O ni sakani Ile Iṣẹ Mọto

AWỌN ẸKA RẸ WA NI: LAGOS · APAPA · IBADAN · KANO · JOS · ENUGU · ONITSHA · ABA

# ORIN MIMỌ TI A FẸRAN

**Lati Ọwọ E. Alabi Thompson**

"Li ọjọ na gan an isun kan yio si silẹ fun ile Dafidi ati fun awọn ara Jerusalemu fun ẹṣẹ ati fun iwa aimọ. Nwọn a si pe oruko mi, emi o si gbọ wọn, emi o wi:e. Awọn enia mi ni; awọn o si wipe Oluwa li Ọlọrun mi." Sekariah ori 13 ẹsẹ 9.

1. Isun kan wa t'o kun f'ẹjẹ,
   To t'iha Jesu yọ
   Elẹṣẹ mo kun ninu rẹ
   O bọ ninu ẹbi

2. Ole Ori Agbelebu
   Yọ lati r'isun na
   N'nu rẹ l'emi pelu si le
   We gbogbo ẹṣẹ mi nu.

3. Jesu aṣẹ bi o kuro
   Ninu ẹjẹ Rẹ lai
   Titi gbogbo 'jọ Ọlọrun
   Y'o fi bo n'nu ẹṣẹ.

4. Gba mo f'igbagbọ risun na
   T'ogbẹ Rẹ ntu jade
   Irapada d'orin fun mi
   Ti ngo ma a kọ titi.

5. Orin t'o dun ju eyi lọ
   Ni ngo ma fi yin Ọ
   Gbat' akololo ahọn yi
   Ba dakẹ n'iboji.

### ITAN ORIN NA

Orin yi jẹ ọkan ti olori onişegun Oyinbo kan fẹran pupọ ẹniti oruko rẹ njẹ Dr. John Good. A ma a kọ orin yi nigbagbogbo ati nibigbogbo, boya larin ile, ni ibiişẹ rẹ, tabi ninu isin agboile. Nigbati o si ma a ku, o pe gbogbo awọn ẹbi rẹ lati teramọ orin yi ni kiko. Paapa ẹsẹ ti o gbẹhin orin yi, o fihan wipe iyin Ọlọrun ko gbọdọ daku lẹnu ẹda titi. Ẹniti o kọ orin na ni William Cowper, o kọ ọ gẹgẹbi ero rẹ nipa igi agbelebu ti a kan Jesu mọ ati ẹjẹ rẹ ti o fi se etutu fun araiye.

## Nwọn gbe ẹjọ ajọmọgbe kan lọ si Kotu Ganran

IKẸJA.

Ni ọjọ Aje ti işe ọjọ kerindinlogun oşu yi ni awọn ọlọpa ba Sanni Salami ti o nta okun ni 23, Alapafuja Street, l'Eko şe ẹjọ niwaju Adajọ-Agba Kotu Kekere kan ni Ikeja pe, o ji Nusi Salami gbe ni Mushin ni ọjọ kẹtala oşu kejila ọdun ti o koja, nwọn ni ni Shomolu ni awọn enikan ti o ri fura si i pe, o ji ọmọ na gbe ti ri i mu. Adajọ si ti gbe ẹjọ lọ si Kotu Ganran.

## Gbẹnagbẹna kan ku s'odo

EKO.

Lẹnulọloyi nigbati okunrin kan ti o nje Rasaki Karimu, ẹni ogun ọdun ti o ngbe Surulere ti o si nşişẹ gbẹnagbẹna labẹ awọn ẹgbẹ Onişowo Kolekole Building Contractors) şiwọ işẹ ni irọlẹ ni o ba bẹ si odo "Queen's Driver", Ikoyi lati luwẹ ki o to dari wa si ile rẹ. Bi o ti nluwẹ ni o ri sinu odo na. Ni owurọ ọjọ Aiku ti işe ọjọ kẹdogun oşu yi ni nwọn ri oku rẹ gbe jade lọ si lakulaku fun ayẹwo.


Ẹ ma a ka Iwe

IROHIN YORUBA

nigbagbogbo fun irohin aladun



**Ohun Orin ti o le mu inu rẹ dun**




PHILIPS

'West African' RECORDS

Awọn ti o nta a ni............
Badejo Stores. 5, Ologun Street, Lagos.
Dayo Development Co. 161, Victoria St., Lagos.
Josey Ola Fajimole & Bros. 21, Balogun Street West, Lagos.
Nwosu Brothers Stores. 24, Asa Road, Aba.

PHILIPS (WA) LTD., P.M.B. 2023, LAGOS



# Ọkọ-elefin mẹjọ larin ọdun mẹta!

Palm Line ngmu Owo Iwo-orun Afirika gbeeru

OLE ni ọkẹ mẹta le ẹgbaarun tọun iwọn ẹru-owo afọko-ko titun ti Palm Line ti fi kun opolopo ọkọ-elefin rẹ larin ọdun mẹta sehin. Nwọn fi irinsẹ akọtun kun inu gbogbo wọn dada, awọn ọkẹ-elefin titun wọnyi nfun awọn onira ati onita lati oke-okun ni anfani işẹ ti o ya. Ti o ni igbẹkẹle ti o si ni inawo diẹ lori gbogbo orisirisi ẹru-owo.




Işẹ wa ni lati ma a ko gbogbo awọn ẹru nyin...

Koo wa fun PALM LINE

# Omi Okun

(Lati oju ewe kerin)

na jafara. Jamba fe se o ni jamba, ohun ti o nso fun Lagido Anikandaje ni pe agbara re po eru si mba on lati ba o ja, nitoripe on koi ri eniti o lagbara to o ri. Lagido si ki i laiya pe ki o ma beru, on yio fun un ni ogun ALUWO ti yio fi se o lose, nitorina mura dada. nso yara lo si tente ori igi pelu ofa mi, se iwo paapa mo pe, mo ti re awon ofa mi, ma fenu kan eje si ni won, baba mi, ma beru ngo fi ofa mi dabira lara won. O yara gungi lo, o loso tente lori igi o nwoye.

**Akiyesi:—Lose to mbo e o ma a ka bi Ijamba ati Ode Amuje ti se tun bere ija. Jamba na ni oruka aluwo ko ran, omo Ode Amuje si ta a ni ofa, o si pa a.**

Olotu mo dupe o, aiye a ye o o.

# Nwọn bi ewele ọmọ kan

ILỌRIN.

LENULỌLỌYI yi ni Amosa Audu, eni ọdun mejidinlọgbọn, ara adugbo Pakata ni Ilọrin bi ewele omo kan loku si Ile-itọju-abiyamọ Ijọba Ibile Ilọrin. Ewele omọ na ni ori meji, apa mẹta—ọkan nfi lati ẹhin rẹ, o si ni ẹsẹ mẹrin. Nwọn tọju oku ewele-ọmọ na si apakan ile-itoju alaisan (Pathology Section). O di ọdun kẹrin sẹhin ti nwon ti soyigi Amosa na ti o bi ewele-ọmọ na.

Ni ọjọ Abameta ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi ni Malam Abdul Kadiri, Ọba Ilọrin ati diẹ ninu awọn osiṣẹ Ijọba Ibile Ilọrin lọ wo oku ewele-ọmọ na.

## Ẹniti o ge aladugbo rẹ leti lọ s'ẹwọn oṣu mẹta

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi ni Victoria Ajiofo, eni ọdun mẹtadinlogun ti o ngbe 28 Abari Court, l'Eko so fun Adajọ Kotu Kekere kan l'Eko pe on jẹbi ọran ti awọn ọlọpa ni on da pe on fi ehin ja eti otun Idowu Salawu jẹ, ni Adajọ ba fi ni ki o lọ se ewọn oṣu meta. Ọgbẹni Y. A. Olọkọ, Agbẹjọro Ijọba sọ fun Adajọ pe ọdaran na daran na nigbati ija kan ṣẹlẹ ati pe nṣe ni o nsalọ pẹlu eti Salawu lẹnu re ki olopa ti o wa nitosi ibiti ija yi gbe ti ṣẹlẹ to ri i mu.

## Karimu siu ẹmọ fun ọkọ

IWO

NI ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu ti o kọja yi ni Ọgbẹni Karimu Adisa sin ọmọ rẹ, Sidikatu Ayoka fun ọkọ rẹ, Ọgbẹni Safiriyu Ile Osa, Oluponna, Iwo. Irohin ko to afojuba ni aṣeye ọjọ na. Awọn alabaṣeyẹ ọjọ na pọ, bi nwọn si ti pọ to yi ni gbogbo wọn jẹ ajẹyo ti nwọn si mu ti pelu.

Die ti aye wa fun ninu awọn alabaṣeye ọjọ na ni awọn Ọgbẹni Saliu Balẹ, Ajile Tanmọsi, Adeyẹmọ Akinẹle, Mọfala Ọlọta, Tayewo Ọlọta, Ajao Wemo Mọnu Ọsaniyi, Kansilọ Ọsaniyi, Akintoye Olukohun, Adeagbo Olukohun, Rufai ati Shittu Alabi

Ẹhin iyawo ko ni mẹni o. Amin.

## Oyeṣọla kọmọjade

AKINMỌRIN—ỌYỌ.

NI ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kejọ oṣu kini ọdun yi ni Ọgbẹni Emmanuel Oyeṣọla ko ọmọkunrin ti Ọlorun fi ta on pẹlu iyawo rẹ, Ọlapeju Ajinun lọrẹ jade, nwọn si ṣe eto isọmọlorukọ lona-esin igbagbọ, nwọn si sọ ọ ni Oyelere Ishọla. Gbogbo ẹsẹ awọn ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹrẹ ilu yi n'o pe sibẹ ṣoṣo bi nwọn ti pọ to yi baba ọmọ na fi onjẹ ati oti tẹ gbogbo wọn lọrun.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn alabaṣeye ọjọ na ni:—Ọgbẹni Joseph Ayanlọla, Alaga Ẹgbẹ Afẹnifẹrẹ ilu yi, Simeon Ikuọla, Elijah Ọladele, James Adeyẹmọ Joseph Adeoye, Joseph Olarogba, Oparinde, Ogundare, awọn Iyaafin Adebisi Ọdẹniyi, Alaga Ẹgbẹ Obirin Afẹnifẹrẹ, Ajeigbe Ogundoyin, Oyekẹmi Alake, Oyewunmi ati Oyewo.

Ki Ọlọrun da ọmọ na si ki O si pin're kari o. Amin.


Iwọ yio ri
i pe ẹwu
rẹ L'OMO JU
OMO Lofi
fọ o



Wo iyatọ larin awọn ẹwu mejeji yi—bẹ ẹ nwọn sese fọ awọn mejeji tan ni! Eyi ti nwọn fọ ninu Omo ni o mọ ti o si tan—O mọ gara to bẹ ẹ gẹ.

Gbogbo awọn ẹwu nyin oloriṣiriṣi awọ ati funfun ni yio si mọ dada ti yio si ma a tan ti o ba fọ wọn ninu Omo.




OMO ni o nfọ aṣọ mọ julọ ni gbogbo agbaiye!



PHENSIC

A ma a wo irora san

AWỌN DỌKITA
NI O MỌ PUPỌJU.




Wa a gbadun, ni kiakia, bi o ba mu Phensic. Egbogi ti o darajulọ fun iwosan ti a nl ni. Fun iba, otutu, ẹsanri ati irora ayokele—mu Phensic. Ri i daju pe o ni Phensic lọwọ ninu ile nigbagbogbo.




PHENSIC

Lagbaraju—yara ṣiṣẹ ju
O si dara ju Aspirin nikan lọ.

